mo wa fi Ẹni ti ẹmi mi n bẹ lọwọ Rẹ bura, ẹ o maa tẹle ilana awọn ti wọn ṣaaju yin

Lati ọdọ Abu Waaqid Al-Laythiy - ki Ọlọhun yọnu si i: Dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nigba ti o jade lọ si Hunayn o rekọja nibi igi kan ti o jẹ ti awọn ọṣẹbọ ti wọn n pe e ni: Dhaatu anwaat ti wọn maa n fi awọn nkan ija wọn kọ ọ, ni wọn wa sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ṣe dhaatu anwaat fun wa gẹgẹ bi wọn ṣe ni dhaatu anwaat, ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa sọ pe: «Mimọ fun Ọlọhun! Eleyii da gẹgẹ bi nkan ti awọn ijọ Musa sọ {ṣe òrìṣà kan fún wa, gẹ́gẹ́ bí àwọn (wọ̀nyí) ṣe ní àwọn òrìṣà kan} [Al-'A'roof: 138] mo wa fi Ẹni ti ẹmi mi n bẹ lọwọ Rẹ bura, ẹ o maa tẹle ilana awọn ti wọn ṣaaju yin».

[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ahmad ni wọn gba a wa]

Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jade lọ sí Hunayn oun ni: Aaye kan ti o wa laarin Tọọif ati Makkah, ti awọn saabe kan si wa pẹlu rẹ awọn ti wọn ṣẹṣẹ wọ inu Isilaamu, Ni wọn ba rekọja nibi igi kan ti wọn n pe e ni: "Dhaatu anwaat", iyẹn ni pe: èyí tí o ni awọn asokọ, awọn ọṣẹbọ maa n gbe e tobi ti wọn si maa n so awọn nkan ija wọn kọ ọ ati awọn nkan miran lati fi wa alubarika, Ni wọn ba tọrọ lọwọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pe ki o ṣe igi kan bii rẹ fun wọn, ti wọn o maa so awọn nkan ija wọn kọ, lati fi wa alubarika; lẹni ti wọn n lero pe alamọri yii lẹtọọ, Ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa ṣe afọmọ ní ti kikọ gbolohun naa, ati ní ti gbigbe titobi fun Ọlọhun, ti o si sọ pe dajudaju gbolohun yii jọ gbolohun awọn ijọ Musa fun un: {ṣe òrìṣà kan fún wa, gẹ́gẹ́ bí àwọn (wọ̀nyí) ṣe ní àwọn òrìṣà kan}, Nigba ti wọn ri awọn ti wọn n jọsin fun orisa ni wọn wa tọrọ pe ki awọn naa ni awọn orisa gẹgẹ bi awọn ọṣẹbọ naa ṣe ni awọn orisa, ati pe eleyii ni itẹle ilana wọn, Lẹyin naa ni o wa funni niroo - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pe dajudaju ijọ yii a maa tẹle ilana awọn Juu ati Kristẹni, ti a si maa ṣe isẹ wọn, lẹni ti o fi n kilọ kuro nibi ìyẹn.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/5927